IROHIN ABO ILU OYINBO AWON OLOTU WA



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO ȘE WI L'EJO



VOL. IX No. 528. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JULY 13, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

## Oloye Fadayiro



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Fadayiro, Apesin Ilaro, ea ni o nlọ ṣe ibẹwo awọn ijoye ati awọn Bale to wa ni Moniya ati agbegbe rẹ. Lẹhin ti o ba pari ibẹwo rẹ tan, yio dari si ile Ọyọ; lati Ọyọ ni yio ti dari pada wa si Ibadan.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbandiger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Ohun Ti Awon Iko Wa Mu Bo Lati Ilu Oyinbo

(O bẹrẹ ninu iwe wa Ọsẹ to kọja)

Nigbati Oloye Awolọwọ fi ọrọ siwaju wipe ki a jeki ilu Eko wa labẹ ijọba Iwọ orun ilẹ Nigeria, Ọgbẹni Benson tako ọrọ na pẹlu awọn isọng̀be rẹ. Nigbati ni Lennox Boyd wa sọ wipe, Igbimọ Lagos Town Council, ti o jẹ wipe ilẹ ni ọ a Eko wa, ibẹ si ni awọn enia ti awọn ara ilu Eko fẹ gbe wa, ti nwọn si nṣe aṣoju fun wọn, a ni lati fi agbara pataki le wọn lọwọ, lati ma paṣẹ lori awọn nkan nwọnyi pẹlu awọn nkan miran ti nwọn tun ma ba ijọba Yoruba ṣe.

Igbimọ Lagos Town Council ni ki o ma paṣẹ nilu Eko ninu awọn ohunkohun ti o ba kan ọrọ Eko, Alafia ati ilera ilu, Awọn ọmọ ti ko lẹkọ, gbogbo ọrọ ti o ba jẹ ti Ọti, ọrọ Cinema, ọrọ ilẹ, gbogbo nkan ti o ba kan ijọba ibilẹ, iwe ti gbogbo enia nka ati ile ibiti a nṣe itọju awọn ohun ataiyebaiye. Nwọn a ni aṣẹ lori awọn apẹja, ati lori gbogbo ọja ti a nna ni agbegbe rẹ, ati lori awọn ẹgbẹ to sowọpọ lati ṣowo. Nwọn a laṣẹ lori Ile ere. Cinima, (Entertainment) ati gbogbo ibi ti a nṣe idaraya, gbogbo irin soke irin sodo mọto larin ilu, ati gbogbo ohun ti o jẹ mọ owo ori

Igbimọ Lagos Town Council ni yio ma fun awọn ọmọ ibilẹ Eko ni iru awọn ti a fi ori rẹ sọlẹ silu Eko ni Ẹbun ẹkọ Ọlọfẹ. Ilu Eko ni lati jẹ agbegbe kan tabi ilu ti a o ṣe ni pataki nibiti awọn aṣoju gbogbo lati agbegbe kakiri yio ti ma ṣe ipade pataki (House of Representatives) A si ti fun igbimọ Lagos Town Council ni aṣẹ lati ni aṣoju ninu igbimọ na, yala ninu igbimọ ilọwọ sowọpọ tabi ninu gbogbo igbimọ ti o le ṣelẹ.

Ninu igbimọ nla Senate ti a fẹ da silẹ Ọba Eko ni lati wa nibẹ, ati ijoye kan ninu awọn ijoye iṣẹ-



ỌBA ADELE II

dalẹ ati awọn enia miran lati inu igbimọ Lagos Town Council, sugbọn ijọba lo ni aṣẹ lati yan awọn enia ti o ba fẹ ni Town Council yi fi Ọba Eko nikan ni lo jẹ ra awọn igbimọ ti enikan ko gbodọ yan, gbogbo igbimọ ni oba Eko dagbi lati lo.

Lana igbimọ Town Council ko si enikan ti oye rẹ gbọdọ tayọ ti Ọba Eko, enikan ko si

(Wo iyoku lọju ewe keji)

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 528. LAGOS, SATURDAY JULY 13 1957


## Siga Mimu Ko Dara

Siga mimu ati ikoko mimu ko nṣe aṣa ti o dara, ẹniti o ba nsaba lati ma mu siga, kole bọ kuro lọwọ arun ikọ, bi oluwa rẹ ko ba si ye ṣe, ikọ na le di akọ aiperi, yio si ma mu ẹjẹ oluwa rẹ dię-dię.

Awọn ẹlomiran a ma sọ wipe, awọn ko le fi siga mimu tabi ikoko mimu silẹ mọ, nitoripe o ti di baraku fun wọn. Siga mimu ko nṣe ohun ti o ṣoro lati fi silẹ. Bi o ba ti denlyan lọkan ara rẹ pe o fẹ gbara rẹ kuro ninu ewu ẹmi kukuru ti siga mimu tabi ikoko mimu ma nko wa ba enia, nṣe ni oluwa rẹ yio mu ọkan rẹ le, yio si ma jẹ akara tabi ki o ma fi nkan miran pa'nu dipo rẹ.

Jamba ti siga nṣe fun enia ko lẹgbẹ, a ma jẹki enia tete di arugbo nipa hihu irun ewu laitọ ọjọ. gbogbo agbari oluwarẹ ni yio ma run fun oruku ewe taba, bi o ba si sun, yio ma da itọ lẹnu, oju ẹni yio si ma ṣu baibai.

Apẹrẹ kan niyi, lati fi han wipe Ọlọrun ko ninu didun si ẹniti o nmu koko tabi siga. Dan apẹrẹ yi wo. Pa Ekute tabi Alangba, ki o fi siga tabi ewe taba bọ lẹnu, sin oku rẹ ki o kọju rẹ si Ila-orun, bi o ba di ọjọ keji, lọ yẹ oku rẹ wo, iwọ yio ri wipe awọn ti yi ọrun rẹ si Iwọ-orun.

Siga mimu ko dara.

---


### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omod

ỌMỌRELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 366. FUN IGO KAN)

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS


## Duke Of Edinburgh



Enitì a nwo aworan re ni apa osi yi ni Oko oba obinrin ti ilu Gesi ti nwon npe ni Elizabeth Keji on lo mura gegebi Oga'ko (Admiral) ninu oko ogun ti o ti nse ise ri, ti oruko re nje H. M. S. Magpie ki o to wa gba oba niyawo.

Nigbara ti o bo lati ona irin ajo re sile Nigeria lo ti ko aso ise wo lati lo wo oko ogun re, wo bi nwọn ti ṣe si. Ọkunrin ọga'kọ (Admiral) ti a nwo lapa ọtun yi ni ẹniti ọkọ ọba na fi ọkọ rẹ le lọwọ, awọn mejeji ni a nwo ti nwọn nfi ọrọ ya ara wọn bi nwọn ti ṣe ọkọ si.

Ọkọ ọba Duke of Edinburgh ni ọga ọkọ H.M.S. Magpie, ẹnikeji ni Commander J G A. Lumsden, ẹniti o gba ipo ọga'kọ ninu oṣu July, 1951.

---

## Awon egbe Adahunse (Herbalist)

### Sile Iwosan titun

Awujọ awọn ẹgbẹ Adahunse titun (Herbalist) ti nwọn so ọrọ pọ ṣe iṣile iṣẹ kan ninu nwọn o ma ṣe iwadi egbogi ati nipa Ifa fun iwosan, enia pọ bi omi ti o wa ṣibẹ, ile Iwosan na wa ni Odo-Ọba, Temidire, ni apa adugbo Kudẹti ni'lu Ibadan. Alaiyeluwa Ọba Olubadan lo ṣi ile na ni ọjọ Ala-misi ọjọ kẹfa oṣu June, 1957.

Ẹniti o ṣiwaju ṣe iṣin iṣile na ni Ọgbẹni Osunṣeyi Ṣobayo ati Olori Awo Ijọ Ọrunmila ti a npe ni Aborẹ. Ọgbẹni S. Onti Ogunloye "Olisa" ti o jẹ baba ẹgbẹ gbogbo-gbo (Supreme Federal President) l'o sọrọ iwuri pupọ nibi iṣile-iṣẹ na.

Diẹ ninu awọn gbajumọ enia ti o wa ṣibẹ ni awọn ọba ati awọn ijoye bẹni Iyalode ilu wa pẹlu Araba Eko ran aṣoju wa pẹlu ẹbun bakanna ni awọn aṣoju wa lati Abẹokuta Ijebu Ikire Apomu ati awọn ilu bebe. Ọwọ nyin a ran o.

# Eja Panla



Nigba ti edekoyede fe be sile larin awon onisowo eja Panla ati awon ti o npa eja na, awon apakan enia so wipe, eja Golugo ni nwon fi nse eja na, awon elomiran si wipe ori eja na dabi ti enia, eyi ni pataki idi re ti nwon se nge ori re sonu.

Sugbon lati mu ki o dani loju wipe ko nse eja keja ni nwon fi nse Panla, Ijoba yan awon oniwe irohin die, ninu won ni Olotu Iwe irohin Eleti - Ofe wa lati lo silu Noway ati Oslo nibiti nwon ti npa, ti nwon si nse eja na.

Ninu aworan yi, ni a ri awon eja panla nibiti nwon gbe saa si, ki o ba le gbe, awon ti a nwo nisale ogba yi ni awon oniwe irohin ti o lo se ofin toto. Idi re ti nwon se wo ewu banku yen ni wipe otutu mu pupo nilu na.

## Ajakale arun se nkase nile

EKO. Fun ọpọlọpọ oṣu ẹhin ninu ọdun ti a wayi, ni a gbọ irohin lati Ileigbo wipe, arun ilẹgbona bẹ silẹ nilu na o si nṣe won bi ọsẹ ti nṣe oju.

Kawi, kaṣọ; ko ju iwọn ọsẹ kan rẹ lọ ni a gbọ irohin pe, okan na ti de ilu Ibadan, ọsẹ ti o si ṣe nilu Ibadan ju ti Ileigbo lọ.

Ko ju iwọn ọsẹ meji lọ, a tun gburo rẹ nilu Eko, asiko na si jẹ eyiti gbogbo awọn ara ilu Eko fẹ ti ere Ẹyọ Adamoriṣa sinku iya Apena, ọba Eko ti gbaṣẹ wipe ṣiṣe ni Ẹyọ yi ṣugbọn ni alẹ ọjọ ti Ẹyọ na ku ọla, ni Dokita Ilera ilu Eko kede wipe, ere Ẹyọ na, ṣaikan ko gbọdọ ṣe nitoripe ilẹgbona ti wọ ilu.

Ilẹgbona yi ẹwẹ ko nfẹ ri ibiti enia parọjọ si pupọ. Bi ere Ẹyọ na iba ti dun to, ikede yi ko gbaye.

### ỌMỌ BIBI ATI OKU

Ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi irinwo-odin-mẹsan ni awọn ọmọ ti awọn bi ni Eko, adorun enia lo si kọja si ọrun alakeji.

### E FUN AWỌN ADUGBO L'ORUKỌ NI ABẸOKUTA

OLOTU.

Gba mi laye Olotu, lati ke si ijọba Iwọ-Orun wipe asiko to nisisiyi ki nwọn fi nomba si ara awọn ile kọkan ati orukọ adugbo gẹgẹbi ti ilu Eko ati Ibadan, nigbana ko ni si iṣina fun alejo lati-tun ma bere ibiti o nlọ. Bi enia ba si kọwe tara ni yio lọ.

A bẹ ẹnyin oṣelu wa ki ẹ ba wa ri si ọrọ yi ki o le dara fun gbogbo wa.

Emi ni,
Ọlayin Dapo

### Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo ẹnyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Ọya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikẹni ti ko ba fi owo wa ranṣẹ ao kọ orukọ re fun Loya Eleti-Ofe, ao ba ṣe ẹjọ ao si gba owo irin ese lọwọ won.

OLOTU

## Awon Oba Ile Yoruba



Nigba atijọ, awọn ọba meji ko gbọdọ fi oju ri ara wọn. Bi nwọn ba fi oju ri ara wọn nkọ? awọn ni ọkan ninu wọn ni lati gbọna ọrun lọ. Lọjọ ti awọn ara ilu Ibadan mu si ile ẹgbẹ Oke Mapo ni Ọgbẹni Capt Ross ba egbogi na jẹ. Nitoripe gbogbo awọn ọba ilẹ Yoruba ti peju si inu ile ẹgbẹ Oke Mapo lọjọ na. Capt Ross sọ pe ni ilu yi, ti ẹnyin ọba ri ara nyin, ti ẹnikan ninu nyin ko si ku lati igba na ni lọ ki awọn ọba ma ṣe ipade Lọba-lọba ni ọdọdun. Eyi na ni nwọn yipada di House of Chiefs.

Akọkọ ṣe ipade Lọba-lọba, ni ilu Ibadan ni nwọn ti ṣe, ekeji ni ile Ọyọ ẹkẹta ni ile Ifẹ, ẹkẹrin nilu Bini.

Ninu aworan ti o wa loke yi ni a ri ọba Ọlọwọ ati ọba Ekiti ninu ipade Lọba-lọba.




# Awon Olorisa Ogun Fajogbon

OWO. Ijoba ki awon enia di molę ninu awon ti o nsin Orişa Ogun lasiko ti nwon nşe odun, nwon ko si gba iduro fun won.

Bi a ti gbo idi oro na si ni wipe nigbati awon aborişa nwonyin nşe odun orişa ogun lowo, gbogbo enia lokunrin ati lobinrin lo duro, ti nwon nworan, olukuluku won lo si şi fila ati gele won dani.

Larin awon ti o duro nwonyi ni okunrin kan ti o nşe iranşę ile işe Ijoba wa, şugbon on yi ko lati şi fila. Nitoripe iranşę kan, ko le sin bgba meji. A gbo wipe nigbati o ko ni nwon ba na a lęgba. Iranşę na si lo fi ejo sun awon olopa.

Awon olopa lo, nwon si ri enia meta mu ninu awon Ologun na. Eyi ko dun mo awon olorişa yi ninu, nwon tun ko ara won jo, nwon lo ka awon olopa mo kotu, wipe ayafi bi nwon ba gba ara won ti nwon mu silę nwon bere si sun ijala, nwon nho gee, awon olopa ba tuto soke ti nwon si foju gba a, ni nwon tun ki awon enia dię molę ninu won fun esun wipe nwon pejo lasiko gba lwe aşę. Nşe ni olukuluku tuka gba ona ibomiran s lo.

# Awon Oyinbo feran aso Yoruba



Asa ibile eni, ko le wun ni, nibikibi ti a ba lo asa Yoruba gegebi asa ibile, nse ni gbogbo awon ajeji enia yio ma pejo wo o. A gbo lenu awon Alhujaji wipe, nigbati eni kan ti o je Alhadji ba de ile Egypt, tabi ni Jerusalem, tabi Istambul, tabi ni Bagdad ati Algeria, bi o ba mura gegebi awon Alhadji ti nmura ni ileyi, ko ni jo eni kan loju, sugbon bi o ba de fila awon Alhadji ti o wo ewu agbada pelu re gbogbo enia ni yio ma wo o.

Bakanna si nilu Oyinbo, bi omo Yoruba kan ba lo aso Yoruba nilu na, nse ni gbogbo awon oyinbo yio ma fi se iranwo.

Ninu aworan oke yi, Oba obinrin bi o ti de ibi apejo kan ti o ri awon omobinrin ile Yoruba, o duro wo won, o si ba won soro pupo nitori o mo wipe lojo ti on ba lo sile Nigeria iru awon ti on lo ba pade nun.

E wo awon yoku ti o wo ewu Kaba, ko tile fe mo wipe nwon mbe nibe nitori ko si ohun ti nwon le wo ti yio jo loju Nitoripe gbogbo iru awon aso bawonni je ti Iran Gesi


SECOND-HAND CLOTHING:-

| | |
|---|---|
| Women's Long Overcoats | 2/6d |
| Women's Short Coats | 1/6d. |
| Women's Dresses and Frocks | 1/- |
| Women's Skirts | 1/- |
| Men's Overcoats, | 6/- |
| Men's Raincoats, Cotton and Gabs mixed | 2/6d |
| Men's Jackets | 2/- |
| Men's Waistcoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/- |
| Police Helmets | 1/- |

Prices quoted ex Warehouses C.I.F. charges extra, Wholesale quantities only. Immediate attention, Write for full prices list, Organs £10, Radiograms £10, Pianos £10, Typewriters £10, Sewing Machines £10,

H. NEWMAN & CO. (MERCHANTS) LTD., 88/92, ELIZABETH STREET, MANCHESTER, ENGLAND



Kere o!

A ti ni origirigi ogun German to sese de, fun onirurn aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos





"AW'OMOLA"

Asiko ooru o ma n ko inira ba omoowo. A ma a sokun nitoripe ko gbadun. Jek o si tutu daradara.

Dr LYNN'S

CHILDREN'S SOOTHING MIXTURE




